# Conversation with Ọladẹjọ Okediji: Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá Látijọ́ àti Lóde-òní.

Olusegun Soetan
Department of Liberal Arts
Pennsylvania University
olusegun@psu.edu

Ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ọ̀jìnmí òǹkọ̀wé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá ní olóògbé Olóyè Ọládẹ̀jọ Òkédìjí jẹ́. Wọ́n kó àkóyawọ́ nínú kíkọ lítíréṣọ̀ Yorùbá. Yàtọ́ sí pé wọ́n jẹ́ ògúná gbòǹgbò nídìí kíkọ lítíréṣọ̀ ajẹmọ́-ìwà-ọ̀daràn, wọ́n jẹ́ òǹkọ̀wé tí ó peregedé nínú kíkọ́ ìtàn àròsọ, eré-oníṣe, àti ewì. Òdú tí kìí ṣe àìmọ̀ fún olóko ní olóyè Òkédìjí láwùjọ àwọn onímọ̀ àti òǹkọ̀wé Yorùbá. Dí òní, ìwé wọn, *Atótó Arére* ní ìwé litíréṣọ̀ Yorùbá tí ó gùn jù lọ. Gẹ́gẹ́ bi òǹkọ̀wé. Olóyè Òkédìjí gbájúmọ́ kíkọ àwọn ìtàn tó jẹ mọ ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ìgbà náà, pàápàá jùlọ àwọn ìwà ọ̀daràn tí ó gbilẹ̀ ní ìlú Ìbàdàn nígbà náà. Bí wọ́n tí kọ àwọn ìwé tó bẹnu àtẹ́ lu ìwà ìbàjẹ́ àwùjọ, bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n lo àwọn ìwé wọn mìíràn láti gba àwùjọ níyànjú. Bákan náà ni wọ́n ṣíṣọ lórí eégún, tí wọ́n sì fi irú ìyà tó ń jẹ àwọn òṣìṣẹ́ hànde. Nígbà tí ogbó dé, wọ́n bẹ̀rẹ̀ síí kọ àwọn èwí tí ó lè fún àwọn òǹkàwé ní ìmísí láti ṣíṣẹ́ takuntakun, àti láti gbani nímọ̀ràn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé olóyé Òkédìjí kò sí láyé mọ̀ lónìí, síbẹ̀, mánigbàgbé ní àwọn ìwé ti wọ́n kọ jẹ́.

Ó kù sáàtà kí wọ́n papòda ní ìfọ̀rọ̀wanilẹ́nuwò yìí wáyé niléé wọn ní ìlú Ọ̀yọ̀, ní ọjọ́ kọkàndínlógún, oṣu kẹwàá, ọdún 2018. Nínú ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò yìí, Olóyè Òkédìjí mẹ́nuba ọgbọ́n ìsọ̀tàn wọn, ìṣòro tó ń dojúkọ lítíréṣọ̀ Yorùbá, àtí ìpèníjà tó dé bá jíjẹ́ òǹkọ̀wé alátinúdá ní àwùjọ wa, àti ní orílẹ̀-èdè Nàíjíríà.

**Ṣoẹtan:** Orúkọ mi ni Ṣẹ́gun Ṣóẹ̀tán, mo jẹ́ òǹkọ̀wé alátinúdá. Mo sì fẹ́ràn láti máa ka àwọn ìwé yín tí ẹ ti kọ gbogbo. Mo máa fẹ́ kí ẹ fún mi ní díẹ̀ nínú àkókò yín láti bèrè ìbéèrè díẹ̀ lọ́wọ́ yín nípa àwọn ìwé tí ẹ ti kọ àti ìrírí yín nípa lítíréṣọ́ Yorùbá. Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa àwọn àgbà ònkọ̀wé Yorùbá tí wọ́n ti ṣiṣẹ́ takuntakun lórí litíréṣọ́ Yorùbá, paápaá jùlọ ìtàn-ajẹmọ́wà-ọ̀daràn/

ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́, ẹ jẹ́ ọ̀kan gbòógì. Ẹni tí a tún lè dárúkọ bí tìyín tí wọ́n jẹ́ èèkàn nínú kíkọ ìwé ìtàn àròsọ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ ni alàgbà Kọ́lá Akiínlàdé. N kò mọ̀ bóyá wọ́n ṣì wà láyé lónìí tàbí bí wọ́n bá ṣì ń kọ ìwé.

**Okediji:** Áà, ó ti kú ù. Ṣé o mọ̀ Ọmọyajowó?

**Ṣoẹtan:** Hún-ùn

**Okediji:** Tí o kọ *Adégbẹ̀san*... Ó pẹ́ tí mo ti gbúrò rẹ̀. Nkò mọ̀ bóyá ó ṣì wà láyé àbí kò sí mọ́. Àlúfàà àwọn Áńgílíkàn ni, bí kò bá ti d bíṣọ́ọ̀bù báyìí. Ọmọyajowó lọrúkọ rẹ̀. Òun náà fi ìgbà kan "Lecture" ní ìfẹ̀ rí.

**Ṣoẹtan:** Màá wá orúkọ wọn lọ.

**Okediji:** Ó ti kọ àwọn ìwé ...Mo rò pé Longman ló báa "publish" ẹ̀. Méjì náà ni mo mọ̀ ní iwé rẹ̀ tó jẹ́ nípa ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́. And, oó rí pé Lápàdé series

**Ṣoẹtan:** Bẹ́ẹ̀ni, sà.

**Okediji:** Kìí ṣe ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ gidi. Ó dàbí iṣẹ́ akitiyan lásán ni. Ó fi ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ kún ún ni. Bíi pé adventure ló fẹ́ẹ̀ jẹ́ ju ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ lọ.

**Ṣoẹtan:** Bẹ́ẹ̀ni sà. Àmọ́ ní èrò tèmi, tí n bá àwọn ìwé Lápàdé, àti bí n bá ń ka, fún àpẹẹrẹ *Owó Ẹ̀jẹ̀*. Bí n bá gbé *Owó Ẹ̀jẹ̀* sí ọwọ́ ọ̀tún tí mo sì gbé Àjàlolẹ̀rù sí apá òsì, èmi gẹ́gẹ́ bí ẹnikàn máa fi ara mọ́ Àjàlolẹrù. Àjàlolẹrù wù mi kà ju *Owó Ẹ̀jẹ̀* lọ.

**Okediji:** Nítorí pé?

**Ṣoẹtan:** Kì í ṣe pé àwọn òǹkọ̀wé méjèèjì kò dáńgájíá. Àwọn méjèèjì fakọyọ nínú ìṣọwékọ̀wé wọn. Àmọ̀ fún èmi, Àjàlólẹrù mú mi mọ̀lẹ̀ bí n bá ń kàá. Mo fẹ́ mọ̀ kí ló fẹ́ padà ṣẹlẹ̀ sí Lápàdé.

**Okediji:** Adeventure nìyẹn.

**Ṣoẹtan:** --Àti Táfá Ìgìrìpá. Lóòtọ́ *Owó Ẹ̀jẹ̀* dà àwọn ìṣẹ́ àwòkọ́ṣe ilẹ̀ òkèèrè tí ó ní ṣe pẹ̀lú ìṣọwọ́kọ̀wé alátinúdá ilẹ̀ òkèèrè.

**Okediji:** Òkú kan yóò ti kú, tí Olúṣínà, àbi kí ni wọ́n t ń péè...

**Ṣoẹtan:** Olúṣínà atọpinpin

**Okediji:** Hùn-ún ùn. Tí yóò wá wádìí bí ó ṣe kú àti ẹni tí ó pa á.

**Ṣoẹtan:** Tí ó dẹ̀ má fi hàn wá pé ìwọ lo pá. Òun máa mú ojú ǹnkan tó ṣókùnkùn , ó máa fi hàn wá pé ẹni ibi leléèyí. Lóòtọ́ iṣẹ́ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ ni, ṣùgbọ́n n ò fi taratara gbà pé iṣẹ̀ Lápàdé jẹ́ adventure lásán, nítorí pé iṣẹ́ Lápàdé kó àkóyawọ́ nínú ṣíṣe ìwádìí ní ìbámu pẹ̀lú àṣà àtí ètò àwùjọ ti ilẹ̀ Nàìjíríà. Mo sọ èyí nítorí pé àwọn ọlọ́pàá wa ò ní agbára tó láti ṣiṣẹ́ bí Ṣínà Atọpinpin ṣe máa ń ṣe iṣẹ́ tirẹ̀ nínú àwọn ìwé Kọ́la Akínlàdé. Fún àpẹẹrẹ, títí di òní. Aò tíì mọ ẹni tí ó pa olóyè Bọ́lá Ìgè, ẹni tí ó ti fi ìgbà kan jẹ́ ọ̀gá àgbà pátá jùlọ fún gbogbo adájọ́ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

**Okediji:** Wọ́n ṣì ń wádìí náà ni [rẹ́rìnín].

**Ṣoẹtan:** Wọ́n ṣì ń wádìí náà ni. Ní ìlú Èkó, ní ọdún mélòó sẹ́yìn, Fúnṣọ Williams, ó kú, a ò mọ ẹni tó pa òun naà.

**Okediji:** Bẹ́ẹ̀ ni.

**Ṣoẹtan:** Àwọn èèkàn èèkàn yìí tí wọ́n jẹ́ oléṣèlú wọ́n kú, wọ́n ṣì ń wádìí náà ni. Àmọ́ tí ó bá jẹ́ pé ìlànà ti Lápàdé ni àwọn ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ń lò láti ṣe ìwádìí wọn, ó ṣe e ṣe, kání lójú ayé, kí Lápàdé àti Tàfá lọ ṣe àwọn ìwádìí yìí, kí wọ́n ti múi àwọn tí ó pa àwọn olóṣèlú mejèèjì tí a dárúkọ lẹ́ẹ̀kàn. Lóòtọ́ iṣẹ́ adventure ni Lápàdé, ṣùgbọ́n a kò gbọdọ̀ gbàgbé pé Lápàdé ní èrò iṣẹ́ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ nínú. Yàtọ̀ sí pé ó ní èrò tirẹ̀, ó mọ láti rò bí ọ̀daràn ṣe lè ronú. Nítorí náà, mo rò pé iṣẹ́ Lápàdé fún wa ní àkànpọ̀ ohun mejì tó fi jẹ́ kó jẹ́ alákàgbádùn. Ó fún wa ní ìmísí iṣẹ́ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ fún èèyàn kan tí ó fẹ́ràn ìṣẹ́ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́, ó sì tún fún wa ní èrò àwọn ọ̀daràn. Nítorí náà.mo gbádùn àwọn ìwé ajẹmọ́-ìwà-ọ̀daràn tí ẹ kọ

**Okediji:** Ṣùgbọ́n Lápàdé máa ń lo ọ̀nà tí kò bá òfin mu [rẹ́rìnín]

**Ṣoẹtan:** [Rẹ́rìnín]. Ṣé tí a bá ní kí ẹ ṣe àtùnṣe sí ẹ̀dá ìtàn Lápàdé, ṣe ẹ máa fi í sílẹ̀ bi ó ṣe wà, àbí ẹ máa sọ ọ́ di ènìyàn jẹ́jẹ́ tí kò fẹ́ràn ìjàngbọ́n?

**Okediji:** Okay. Jẹ́ ki n ṣàlàyé method mi fún ẹ generally. Èmi máa mú ẹ̀dá-ìtàn tí máa fi han aráyé. Òun nìkan ni máá kọ́kọ́ fi han aráyé. Ìṣẹ̀lẹ̀ kan á wá a bá a. Ohunkóhun ló lè jẹ́. Á wá báa tó jẹ́ pé ó ku pé báwo ló ṣe máa jáde níbi tí ó wà.Ìṣẹ̀lẹ̀ yẹn lè jẹ́ ènìyàn, àwìjọ; ó lè jẹ́ nǹkan-kí-ǹǹkan tó máa tako ẹ̀dá-ìtàn tí mo gbé síta yẹn. Bí wọ́n ṣe máa wá kọ lu ara wọn, òhun ni òǹkàwé á máa wò. Báwo ni wọ́n ṣe máa kọlu ara wọn. Tí wọ́n bá kọlu ara wọn, kí ni ìpèníjà tó máa bá wọn. Ẹnìkíní àti ẹnìkejì. Bí ìkọlù yẹn bá ṣe pọ̀ tó sí ni ìwé ṣe máa gbádùn mọ́ àwọn òǹkáwé sí. Wàhálà tó dé lááárín àwọn méjèèjì yìí—Atiku àti Buhari—kí n gbé wọn kalẹ̀ báyìí [rẹ́rìnín]

**Ṣoẹtan:** [Rẹ́rìn-ín]

**Okediji:** N ò ní mọ ibi tí ìtàn yẹn máa parí sí. Ṣùgbọ́n máa wá jẹ́ kí wọ́n máa bá ara wọn ta. Bóyá ọ̀rọ̀ tí wọ́n ń sọ, bóyá oúnjẹ tí wọ́n fẹ́ jẹ, bóyá ǹnkan mìí ṣẹlẹ̀ sí wọn. Ǹkan kan: bó ṣe máa lọ nìyẹn. Ṣùgbọ́n Lápàdé "will always be Lápàdé to me." Bí ó ti máa ṣe nìyẹn, áa rí ìṣẹ̀lẹ̀ kan, bóyá ẹnikan ló máa sọ fúnún bí irú Angelina, òun ló wá báa. Ní ọ̀nà mìíràn ní Jọláadé àti Láídé fi wá báa. Irú ǹnkan náà ni. Wọ́n ání pé ìṣòro tí a mà ní rè o. Òun máa wá gba ìṣòro yẹn tí wọ́n mú wá bí ẹni pé tiẹ̀ ni. Á wá máa wọn ọ́nà àti yanjú ẹ̀. Kí ni ìṣoro tí ẹ gbé wá yìí, kí la ṣe máa yanjú ẹ̀. Nítorí náà, Lápàdé ò lè yàtọ̀ sí Lápàdé, ní ẹni tí èmé mọ̀. Mo ti ṣẹ̀dá ẹ̀dá-ìtàn pé Lápàdé rèé. Èèyàn fẹ́rẹ̀ lè ri ní títì pé òun ló ń lọ yẹn.

**Ṣọẹtan:** Bákan náà pẹ̀lú Tàfá Ìgìrìpá àti Súlé dẹ́ríbà

**Okediji:** Bẹ́ẹ̀ ni.

**Ṣọẹtan:** Tí a bá kà á dé ibìkan, mo máa ń bèèrè pé ṣe olóyè ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn èèyàn kan tí wọ́n wá wò wọ́n láti ṣẹ̀dá àwọn ẹ̀dá-ìtàn wọn ni. Ìdí tó mo fi ro irú èrò yìí ni pé nígbà tí mo jẹ́m ọmọdé, ọ̀gbọ̀ni kan wà ní àdúgbò wa ní Abẹ́òkúta tí ìrísí àti ìhùwàsí rẹ̀ jọ ti Tàfá lájọtán. Ní èrò tèmi, ìtàn Lápàdé kò pé láìsí Tàfá.

**Okediji:** Bẹ́ẹ̀ ni

**Ṣọẹtan:** Kí ni ìdí tí ẹ fi ṣẹ̀dá ẹ̀dá-ìtàn tó ń jẹ́ Tàfá Ìgìrìpá gan-an?

**Okediji:** Okay, Lápàdé ń ti oko bọ̀ ni ìṣẹ̀lẹ̀ yẹn ṣẹlẹ̀. Ó ríi pé wọ́n lọ bo owó kan mọ́ ibìkan. Bí ó ti wá jẹ́ ìṣẹ̀dà tiẹ̀ tí mo gbé wọ̀ọ́, ó lọ síbẹ̀, ó sì ri pé kìí ṣe owó ẹ̀tọ́. Ó dàbí owó soakway. Ó sì kó o. Kí ó tó kó o, ẹni tí o fi owó pamọ́ náà dé bẹ́, wọ́n sí jọ ṣe kópọ̀ láàárín ara wọn. Ó soó mọ́ igi níbẹ̀. Ó padà déle. Èrò yẹn wá wá níní ọkàn rẹ̀ pé kí lòun ṣe ṣe kiní yìí oo. Ó pe Dàda, ọmọ tí ó ń gbé ọ̀dọ̀ ẹ̀. Ṣé o mọ Tàfá, ẹnikàn tí ó rò pé ó lè ran òun lọ́wọ̀ níbí bí wọ́n ṣe lè wádìí kiní yìí. Dàda ní òun mọ̀ọ́ ní Òkè-Olúòkun. Ó ní kí ó lọ bá òun pèé wá.

**Ṣọẹtan:** Ẹ má bínú bàbá Olóyè. Òkè-Olúòkun. Mo wà LỌ̀yọ̀ọ́ báyìí, bí a bá ń ṣe àpèjúwe ilé àwọn Lápàdé, agbègbè ibo ni ilé àwọn Tàfá máa wà? Àbi ní Ìbàdàn lọ́hùn ún ni?

**Okediji:** Ìbàdàn ni. Ní ìdí aró. Gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ ni ilé-ẹ̀kọ́ Wesley, ìdí-aró kò jìnnà sí Elékùrọ́ ní Kọ́lẹ́ẹ̀jì wa. Ni ó jẹ́ kí n mú ìbẹ̀ yẹn gẹ́gẹ́ bí ilé Tàfá. Ṣé ó wá rí Òkè-Olúòkun yẹn, òhun ni ilé Adélabú, bàbá Adélabú tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ wá mú láti wá dupò gómìnà Ọ̀yọ́ báyìí. Adélabú le gẹ́gẹ́ bí èèyan; nítorí náà ni mo ṣe lọ mú ẹnìkan nínú ilé rẹ̀. Òun ni Tàfá Ìgìrìpá yẹn. Wọ́n fẹ́ràn Adélabú ni Ìbàdàn gidigidi nígbà yẹn lọ́hùn ún, ṣùgbọ́n èèyàn líle burúkú ni. Líle rẹ̀ pọ̀.

Ó pọ̀. Òun ò wá ṣe lò bí kò bá ń ṣe ọmọ kan nínú ilé ẹ̀. Òkè-Olúòkun yẹn kò jìnnà sí Gbọ̀ngàn Màpó. Ó wà níbẹ̀ dòní. Fún bẹ́ẹ̀, ilé yẹn ni Lápàdé tí ó ti ṣe ọlọ́pàá rí lọ ronú pé òun yóò nílò ẹnikan tó lè dojúkọ ìṣẹ̀lẹ̀ tó dé bá òun, ló fi lọ múu. Nítorí náà. Mo ṣẹ̀dá Lápàdé lọ́tọ̀, ó wá ronú pé òun yóò nílò ẹnìkan tó le nítorí ó fojú ròó pé àwọn ọlọ́pàá wọ́yìí kò lè ṣe ìwádìí tí òun bá ní kí òun gbé ọ̀rọ̀ yìí lé wọn lọ́wọ́, wọ́n ó kàn bájẹ́ ni. Nítóri náà ó wá rò pé òun máa ṣé fúnra òun, ló ṣe pe Tàfá. Tàfá tó pè, nígbà tó di pé ó nílò mọ́tọ̀, n ló fa Súlè.

**Ṣoẹtan:** Ẹ má bínú pé mo gba ọ̀rọ̀ mọ́ yín lẹ́nu. Gẹ́gẹ́ bí ẹ ti sọ pé Wesley Kọ̀lẹ̀jì lẹ ti kàwé, ẹ lo àdúgbò kan tí kò jìnnà sí ibi tí ẹ ti kàwé, tí ẹ sì yọ ẹnìkan láti ínú ilé Adélabú láti dúró fún Adélabú tí àwọn Ìbàdàn nífẹ̀ẹ́ sí, ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ ènìyàn líle, báwo ni ti Súlè Aláyìmọ́ọ̀ ṣe jẹ́? Ṣé ẹ mọ ẹnìkan tí ó mọ ọkọ̀ wà gan an ni, àbí ẹ kàn ṣẹ̀dá òun náà ni?

**Okediji:** Ìṣẹ̀lẹ̀ ló dé tí a fi nílò ẹnìkan tí ó gbọ́dọ̀ mọ ọkọ̀ wà. Èmi ò fi ọkàn sí ẹnìkan kan ṣáájú ìyẹn. Ṣùgbọ́n Tàfá ló dárúkọ ẹ̀ fún Lápàdé pé tí ó bá ṣe pé ẹni tí ó ń wá, ẹnití kò sí òhun tí eléyìí kò lè gbé pamọ́. N kò mọ ẹnikẹni bẹ́ẹ̀ yẹn. Nígbà tí mo bá múra láti kọ̀wé, èmi kìí ní àjùbà, ìyẹn ni pé kí ènìyàn ti kọ pé báyìí ló máa rí. Àwọn ẹ̀dá-ìtàn yẹn ni màá jẹ́ kí wọ́n máa kọlu ara wọn bí ìtan bá ṣe ń tẹ̀síwájú.

**Ṣoẹtan:** Kí ló dé tí ó fi jẹ́ Lápàdé ni ẹ pe Lápàdé? Kí ló dé tí ẹ kò fún ni orúkọ mìíràn? Ṣé láàárín àwọn ẹgbẹ́ yín nígbà náà ni orúkọ náà ti wá, àbí ìrírí ló fàá?

**Okediji:** Nígbà tí mo kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ sí kọ̀wé, bí mo ṣe máa ń ṣe náà nìyẹn. Mò ń rò pé orúkọ wo ni mo máa fún ẹni tí ó le yìí o. Mo wá wà ní, 1954 ni mò ń sọ yìí o, ni ilé-ìwòsàn gbogbogbò ní Àkúrẹ́ lọ́jọ́ yẹn. Àwọn obìnrin méjì kan dé, wọ́n pe nọ́ọ̀sì , wọ́n ní àwọn ń bèrè ọ̀gbẹ́ni Lápàdé! Nọ́ọ̀sì ni: Háà, dọ́kìtà Lápàdé lẹ pè bẹ́ẹ̀yẹn? Ibi tó ti jẹ símì lọ̀kàn nìyẹn pé mo lè lo orúkọ rẹ̀. N ò mọ Lápàdé yẹn rí. Ṣùgbọ́n fún ẹnìkan tí àwọn nọ́ọ̀sì ń pé hàà hàà, Lápàdé lo pè bẹ́yẹn. Misita làwọn tibí pèé. Mo wá wòó pé eléyìí tó ṣe olú-ìtàn. Bí mo ṣe mú u nìyẹn. Wo *At*ótó Arére, “Pàṣípààrọ̀” ni mo kọ́kọ́ fẹ́ pè é. Ẹni tí ó ṣẹ̀ kọ́ ló jìyà, páṣípààrọ̀ rẹ̀ ni. Bí mo ti wá jókòó níjọ́ yẹn tí mo fẹ́ máa kọ ọ́ ni rédíò tí a máa ń so mọ́ ara ògiri ilé nígbà yẹn fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ètò kan lọ́sànán yẹn. Lẹ́yìn tó ti kọrin ìbẹ̀rẹ̀ ètò: tatáátá tatááta, tatáá ta táta! Atótó Arére! Mó dì í mú pé eléyìí lè jẹ́ àkọ́lé ohun tí mo fẹ́ kọ yìí. Nígbà tí mo ń kọ *Rẹ́rẹ́ Rún*, N ò mọ̀ bóyá o ka *Rẹ́rẹ́ Rún*?

**Ṣoẹtan:** *Rẹ́rẹ́ Rún* ti Láwúwo? Bẹ́ẹ̀ ni!

**Okediji:** Hùn ún ùn. “Ọwọ́ tẹ Àgádágodo Wọn” ni mo kọ̀kọ̀ fẹ́ pè ìwé yẹn. Ṣùgbọ́n atọ́nà mi kan nípa kíkọ ìwé eré-oníṣe nígbà yẹn, Olóògbé Ọlá Rótìmi,

ẹni ti ó kọ *The Gods Are Not to Blame*. Mo ti kọ ìwé náà tán, kí wọ́n tẹ̀ẹ́ ló kù, ìgbà tí Láwúwo bẹ̀rẹ̀ sí sọ rẹ́rẹ́ rún o! Rẹ́rẹ́ mà rún o, ló wá ní pé àkọ́lé yẹn dára ju "Ọwọ́ tẹ Àgádágodo Wọn" tí mo kọ́kọ́ ń pè é. Ọ̀pọ̀ àwọn nǹkan wọ́nyìí kì í ṣe àmọ̀ọ̀mọ̀ ṣe. Ìṣẹ̀lẹ̀ kan tó bá wáyé ní àkókò kanló máa fún mi ní àkọ́lé tàbí ìṣesí ẹ̀dá-ìtàn tí mo mú wá. Ohun tó bá ṣẹlẹ̀ nígbà yẹn ló máa ń jẹ́ kí ó dàbí òótọ́ lójú òǹkàwé . Nitorí pé èmí ò faramọ́ pé èèyàn wà nínú ibì kan báyìí nísinsìnyí, kò wá mọ bí ó ṣe máa jáde, ó wá fẹ̀yìn tògiri , ó wá bẹ̀rẹ̀ sí pọfọ̀. Ó wá jáde! Èmi ò fara mọ́ ọn. Máa jẹ́ kò rò pé báwo ni òun ṣe lè jáde yìí o! Yóò gbìyànjú àwọn ojú fèrèsé. Bí èmi ṣe máa ń ṣe nìyẹn. Bí ìṣẹ̀lẹ̀ kan bá dé tí ẹnití mò ń sọ ìtàn rẹ̀ bá dàbí ẹni pé ó fẹ́ há, ẹni tí ó ń kàwé á fẹ́ wo bí ó ṣe dọ́gbọ́n jáde. Tí n bá ní wọ́n yìnbọn síi, N ò ní sọ pé ó pọfọ̀ kí ayẹta yẹ ọta. Èmi ò ní sọ bẹ̀ẹ̀. Olóògbé Akinwunmi Ìṣọ̀lá á sọ pé kiní yẹn wà ní ilẹ̀ Yorùbá, pé wọ́n lè pọfọ̀. Wọ́n lè ṣé e. Èmi ò sọ pé wọn ò lè sé, ṣùgbọ́n èmi kò níi lò ó

**Ṣoẹtan:** Ní kíákíá sà, ẹ jẹ́ kí á sáré mẹ́nuba ìyẹn. Kí ló dé tí ẹ fi kìí ṣe àmúlò agbára àbáláyé wọ́nyìí nínú iṣẹ́ yín? Kí ló dé tí ẹ kò gbàgbọ́ ní ìgbàgbọ́ nínú wọn?

**Okediji:** Kì í ṣe ọ̀rọ̀ ìgbàgbọ́ [wúkọ́]. Mo ti sọ ohun tí ó jọ bẹ̀ẹ̀ lẹ́kànan. Nígbà tí àwọn kan bi mí pé ṣé mo ti ṣiṣẹ́ ọlọ́pàá rí ni. Ó tì, n kò ṣe ọlọ́pàá rí. Ṣùgbọ́n mo mọ bí ọlọ́pàá ti lè ṣe. N kò mọ́ nípa àwọn òògùn wọ́nyìí. Èmi ò mọ̀ nípa wọn rárá. Á ṣòro fún mi láti lè lòó lọ́nà tí òǹkàwé á fi gbà pé òótọ́ ni. Èmi ò mọ̀; ohun tí ń kò bá sì mọ̀, n kò le sọ pé ó ṣẹlẹ̀. Ó ṣeé ṣe. Ṣùgbọ́n èmi mọ̀ pé èèyàn lè gbé ilé ayé yìí láì jẹ́ pé ó pé ọfọ̀. Èyí tí èmí rí nìyẹn. Òhun ni èmi sì màa kọ. N ò ní kọ èyí tí n kò rí.

**Ṣoẹtan:** Ẹ ṣé fún ìdáhùn yín. Ìwé yín kan wà tí ó máa ń gbomijé lójú mi fún ẹ̀dá-ìtàn tí ó ń jẹ́ Àlàbá. Ṣé lára ìrírí náà ni ẹ fi kọ ìtàn Àlàbá, àbi ìmísí náà ni? Ní tèmi, n kò rò pé Àlàbá tọ́ sí gbogbo ìyà tí ó jẹ nínú ìwé Atótó Arére.

**Okediji:** Ó dára. Bí kò ti yẹ kí Láwúwo àti ìyàwó ẹ̀ jìyà. Ṣùgbọ́n ti Àlàbá yẹn, ní around 1975 tàbí 76, tẹlifíṣàn ni mò ń wò báyìí lọ́sànán ní Ifẹ̀. Ìfẹ̀ ni mò ń gbé nígbà yẹn. Mò ń wo tẹlifíṣàn báyìí ni wọ́n de olè kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Oyènúsì mọ́ òpó, tí wọ́n sì yìnbọn lù ú tó fi kú. Ọkàn mi wá lọ sí pé kí ni sọ ọmọkùnrin da irú eléyìí. Kí ní ń mú ọmọkùnrin tí ó fi di pé ó ń lọ jalè, ó ń lọ ṣe oríṣiríṣi tó fi di pé wọ́n fi múu wọ́n sfi wá yìnbọn lùú báyìí. Ni mo wá rò pé bóyá "broken family" ló lè fàá. Ṣùgbọ́n mo wá gbée kúrò. Kì í wá ṣe Àlàbá lèmí fi síbi tí wọ́n yìnbọn lùú mọ́n-ọ́n, ọ̀rẹ́ rẹ̀ Sámínù ni mo wá fi síbẹ̀. Bí mo ti bẹ̀rẹ̀ ìwé yẹn gan an ni bí wọ́n ṣe pa Oyènúsì. Ó wá di pé báwo ni ọmọkùnrin ṣe lè dé irú ibi tó dé yìí. Ni mo ṣe wá gbé Àlàbá lọ sí abà wọn ní Ìmìní. Ìmíní ò jìnnà sí Ọ̀yọ́ níbí yìí. Mo wá gbé lọ sí ibẹ̀ níbi tí bàbá àti ìyá rẹ̀ ti kọ ara wọn. Débi pé bàbá rẹ̀ fẹ́ ìyàwó mìíràn tí ó ń fi ara ni Àlàbá kó tó di

pé ó sálọ. Ìṣẹ̀lẹ̀ tí èmi bá rí , irú Oyènúsì yẹn ló fa *Atótó Arére*. Kí á wá sọ pé ó pọfọ̀ kúrò níbẹ̀ lọ́jọ́ náà. Akínwùnmí ní ó ṣe é ṣe, pé a ò rí i ni. Èmi ò rí i. Òun lè ti rí i rí, ṣùgbọ́n èmi ò rí i.

**Ṣoẹ̀tan:** Síbẹ̀, mo rò pé ẹ ṣì fìyà jẹ Àlàbá nínú Atótó Arére. Kí ló dé té ẹ ṣe bẹ́ẹ̀ fún un? Kí ló dé tí ẹ kò fún ní àǹfàní láti bẹ̀rẹ̀ ayé ọ̀tun? Ṣé tí ẹ bá fẹ́ tún Atótó Arére kọ lónìí, ṣe ẹ máa yí ìgbẹ̀yìn ayé Àlàbá padà sí bí ẹ ṣe parí ẹ̀ nínú ìwé náà?

**Okediji:** Ó tì! Èmí rò pé kò yẹ kí Àlàbá gbádùn owó tó jí yẹn. Nítorí pé tó bá padà dé oko Ìmìní, owó yẹn pọ̀jù ohun tó lè máa ná lóko. Irú ayé wo ló máa máa gbé ní Ìmìní. Mo ti ṣe àtùnṣe kan sí Rẹ́rẹ́ Rún nítorí pé àwọn èèyàn ń sọ pé kò yẹ kí Láwúwo jìyà bẹ́ẹ̀ yẹn kú. Ṣùgbọ́n nínú àtùnṣe tí mo ṣe yẹn, àwọn òṣìṣẹ́ wọ́n wá jà fitafita. Wọ́n ṣe, ṣùgbọ́n síbẹ̀ síbẹ̀, àwọn ìjòyè náà ló tún borí wọn. Láwúwo tún jìyà yẹn gbé náà ni. Nítorí pé ìyẹn ni "reality" lójú tèmi. "It is the reality today." Gbogbo ibi tí àwọn èèyàn bá ti ń sọ̀rọ̀ Rẹ́rẹ́ Rún, àwọn òṣìṣẹ́ ó kàn má jìyà ni. Kò sì lè tán. Bẹ́ẹ̀ ló máa ṣe wà títí láé. Àwọn Ará Rúṣíà àti Faransé, wọ́n jìjà ìjàgbara, ti Rúṣíà tíẹ̀ gbé dé ibi kọmúnisìn. Nígbẹ̀yìn kọmúnisìn náà tún forí ṣánpọ́n ni. Lónìí kò sí láyé mọ́. Bóyá díẹ̀ ní China àti Kúbà. Àwọn òṣìṣẹ́ ló máa máa jìyà títí láéláé. [Rẹ́rìn-ín].

**Ṣoẹ̀tan:** Ó ba nilọ́kàn jẹ́ pé òṣìṣẹ́ ló máa jìyà nígbà gbogbo.

**Okediji:** Àwọn òṣìṣẹ́ ò lè rẹ́rìn-ín. Bí ilé-ayé ti rí nìyẹn. Èmi ò nìí kọ pé àwọn òṣìṣẹ́ wá borí àwọn tó gbà wọ́n síṣẹ́.Tí mo bá kọ ọ́ báyẹn, á jẹ́ pé n kò sọ òtítọ́. Mo gbà pé ayàwòrán ni òǹkọ̀wé. Ohun tó ń rí ló ń yà. Ohun tí kò bá sí níbẹ̀, kò lè yà á. Ó wá lè délé kí ó máa wá ṣe àtùnṣe, kí ó má lo àyínìke. Ṣùgbọ́n nǹkan tó rí gan an kọ́ yẹn. Ó burú pé àwọn òṣìṣẹ́ kò lè ṣẹ́gun àwọn agbanísíṣẹ́, ṣùgbọ́n òtítọ́ nìyẹn.

**Ṣoẹ̀tan:** Ọ̀jọ̀gbọ́n Akínwùnmí Ìṣọ̀lá gbà pé ó pọn dandan kí òǹkòwé ó ṣàfihàn àṣà nínú iṣẹ́ rẹ̀

**Okediji:** Ṣé ìyẹn pọn dandan?

**Ṣoẹ̀tan:** Ìbéèrè náà nìyí pé: ṣé ó jẹ yín lógún pé a gbọ́dọ̀ ṣafihàn àṣà Yorùbá nínú àwọn iṣẹ́ alátinúdá yín?

**Okediji:** Ayàwórán ni mi. Ohun tí mo bá rí lawùjọ ni mo máa kọ. Nítorí náà bí àṣà bá yọ jáde, déédé. Irú iwé Lápàdé, ǹ jẹ́ a tilẹ̀ rí ǹǹkan kan tí ó jẹmọ́ àṣà Yorùbá níbẹ̀?

**Ṣoẹtan:** Bẹ́ẹ̀ ni. A rí àwọn àpẹẹrẹ díẹ̀díẹ̀ níbẹ̀ pẹ̀lú bí Lápàdé ṣe ń ra ẹ̀bùn wá fún àwọn ìyàwó ilé wọn, àti bí àwọn ìyàwó agboolé wọn náà ṣe ń bọ̀wọ̀ fún un.

**Okediji:** Òun gan an, bí ó ṣe joogún oko bàbá ẹ̀, ara àṣà Yorùbá ni. Ìwé kan wà tí kò sí lorí àtẹ mọ́ báyìí, *A*ájò Ajé. Ara àwọn ìwé mi ni. Nínú *A*ájò Ajé, agbo kan ń ta tẹ́tẹ́, wọ́n sì ń wá ọ̀nà tí wọ́n yóò fí máa jẹ. Wọ́n lọ bá aláàfáà: òun kéwú fún wọn. Ìyẹn ò sọ pé mo gba ohun tó ṣe gbọ́. Wọ́n lọ bá babaláwo, òun náà fi tiẹ̀ fún wọn. Wan lọ bá pásítọ̀, wòlíì, òun náà ṣe tiẹ̀ fún wọn. Wọ́n tún ronú Kọ̀ǹpútà; wọ́n tún lo ìyẹn náà. Lẹ́yìn-ò-rẹyìn, wọ́n jẹ. Èwo ló jẹ́ kí wọ́n jẹ nínú gbogbo wàhálà wọ̀nyìí? Ohun tí kámẹ́rà mi rí nìyẹn. Fún èmi, ẹ̀dá-ìtàn ni màá gbé kalẹ̀, tí màá wá jẹ́ kí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ oríṣiríṣi ó máa kọlu ara wọn.

**Ṣoẹtan:** Lóde òní, Lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá ti ń kásẹ̀ nílẹ̀, àwọn ìran tó ń bọ̀ lẹ́yìn ò sì fo bẹ́ẹ̀ gbájúmọ́ kíkọ lítíréṣọ̀ Yorùbá. Kí ni èrò yín lórí lítíréṣọ̀ Yorùbá báyìí báyìí?

**Okediji:** Kò sí lítíréṣọ̀ Yorùbá gidi mọ́ lórí àtẹ lódé òní nítorí pé nígbà tí àwí fi ń kọ̀wé, ìwé wùú wà kọ ni. Nísinsìnyí, kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́. Àwọn tí wọ́n ń kọ̀wé nísinsìnyí, tí o bá wòó, olùkọ́ ni wọ́n ní ilé-ẹ̀kọ́. Nígbà tí ìjọba sì ti wá gbà pé àwọn làwọn ó máa mú ìwé tí wọn ó máa kà. Ìjọba ló ń muú nísìnsìnyí. Nígbà tí èmi ń ṣiṣẹ́ olùkọ́, mo ní àǹfàní láti yan ìwé kan tí mo bá rí pé ó dára fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́.Ṣùgbọ́n n ò mọ ohun tí WAEC àti NECO (ìyẹn àwọn àjọ tó ń mójútó èto ìdánwò ní ilé-ẹ̀kọ́ girama) máa ṣe. Ṣùgbọ́n èmi a ti kọ́kọ́ jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ó ti mọ̀ nípa àwọn ojúlówó ìwé lítíréṣọ̀ Yorùbá.Ni ọjọ́ kan ní Ifẹ̀, ẹnìkan wá bá mi bí ìwọ náa ti wá, ó jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní Yunífasì Ìlọrin. Nígbà tí ó ń bèrè ọ̀rọ̀ lọ́wọ́ mi, mo ríi pé ìmọ̀ tí ó ní kéré gáà nípa lítíréṣọ̀ Yorùbá. Mo wá bií pé ìwé wo ló ti kà fún liítíréṣọ̀ Yorùbá. Ó wá ni olùkọ́ àwọn kan ló kọ ìwé tí àwọn ń kà. Ó sì jẹ́ ẹyọ kan. Ó rẹ̀ mí dẹ. Nítorí nígbà tí àwọn ọmọ mi ń ṣe Yorùbá ní Yunifásítì, bí ìwé ò ti ṣe pọ̀ tó nígbà yẹn, ní sáà ka, wọn a máa ka méjìlá. Tí òun wá ni òun ń ṣe "project"lọ́wọ́ tí ó wá so pé ìwé kan náà tí òun ti kà nìyẹn. Nísinsìnyí, ìjọba ló ń mú ìwé tí àwọn ọmọ yóò fi ṣe NECO àti WAEC. Ohun tí ó wá ń ṣẹlẹ̀ ni ẹnikan á gbé ìwé kan lélẹ̀, á a kọ "ó ó ó ó'si, á sì kọ orúkọ ara rẹ̀ si, á wá lọ gbe fún wọn ní ilé-iṣẹ́ ètò ẹ̀kọ́, á sì tọwọ́ bàpò, á fún wọn lówó. Ilé-ìṣẹ́ ètò ẹ̀kọ́ á sì sọ pé ìwé yẹn ni wọ́n máa kà ní àwọn ìpele ẹ̀kọ́ girama. Nítorí náà, kìí ṣe pé àwọn òṣìṣẹ́ ilé-iṣẹ́ ètò ẹ̀kọ́ jókòó láti ṣe àpérò lórí irú ìwé tí o yẹ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ó kà, àwọn èèyàn ló lọ ń bá wọn, tí wọ́n ń gbé owó fún wọn láti yan ìwé. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn olùkọ́ ní ilé-ẹ̀kọ́ ló ti di òǹkọ̀wé tí wọ́n ń kọ oríṣiríṣi. Mo ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn nínú yàrá ìkàwé mi; wọn ò dára rárá. Owó ti ba nǹkan jẹ́. Owó ló kù tí wọ́n fi ń mú ìwé tí àwọn ọmọ yóò kà. Àwọn olùkọ́ wọn náà wá lè fi tìwọn kún àjọ elétò ẹ̀kọ́.

**Ṣoẹ̀tan:** Háà! abájọ! ìdí nìyí tí wọ́n kò fí ń ka àwọn ìwé irú yín, Olóògbé Fágúnwà, Ọlábimtań, àti Olúbọ́rọ̀dé.

**Okediji:** Wọn ò ka wọ̀nyẹn mọ́. Wọn ò sí ní ilé-ẹ̀kọ́ mọ́ [rẹ́rìn ín]. Bó ti wà nísìnsìnyí ...ọdún méjìlá ni mo fi máàkì ìdánwò WAEC. Ìwé ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n sì ń mú lọ́dọọdùn nígbà náà. Gbogbo ìwé nísnsìnyí, pelebe pelebe, ó pọ̀jù àádọta sí ọgọ́ta ojú-ìwé. Kí ló lè í àwọn yìí padà? Ó bẹ̀rẹ̀ lọ́wọ́ ìjọba. Nígbà tí mò 'm máàkì ìdánwò WAEC, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ Yorùbá nígbà náà gbọ́dọ̀ ṣe ìdánwò lórí èdè àti àṣà Yorùbá. Ìdánwò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ sì ni wọ́n. Ṣùgbọ́n lónìí, wọ́n ti pa méjèèjì pọ̀. "o dàbi pé wọ́n ti ẹ gbájúmọ́ èdè ji lítíréṣọ̀ rẹ. Ìrètí dà? Níbo ló wà?

**Ṣoẹ̀tan:** Ṣẹ akitiyan wà té ẹ́yin àgbaà òǹkọ̀wé Yorùbá lè ṣe, pàápàá jùlọ pé ṣé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wà ẹ̀yin àgbà máa ń ṣe fún àwọn òǹkọ̀wé tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dìde nílẹ̀?

**Okediji:** Nínú ẹgbẹ́ òǹkọ̀wé, tí a bá ń ṣe ìpàdé, a máa ń ní ọjọ́ kan àgbà òǹkọ̀wé kan yóò bá ìjókòó sọ̀rọ̀ lórí bí òun ṣe ń kọ̀wé, bí èèyÀn ṣe lè kọ̀ọ́ kó dùn ún kà. Ṣùgbọ́n àwọn tí à ń bà sọ̀rọ̀ yìí náà, àwọn náà ni tíṣà tí ó wà ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ tí a sọ nípa wọn. Kí ni wọ́n fẹ́ fi irú ìmọ̀ yìí ṣe? Owó ni wọ́n ń wá!

**Ṣoẹ̀tan:** Mo Ṣàkíyèsi pé ǹnkan tún burú ní apá ewì kíkọ ju ti eré-oníṣe lọ. A fẹ́rẹ̀ má rí ìwé tó ṣe mú yangàn lórí ewì lóde òní. Kí ló fà á?

**Okediji:** Lóòótọ́, àwọn àgbà akéwì bí Adébáyọ̀ Fálétí ti lọ, ṣùgbọ́n a ṣì ní àwọn ògbóǹtarìgì bíi Ọlánréwájú Adépọ̀jù àti Túbọ̀sún Ọládàpọ̀. Àwọn èèyàn ò lọ bá irú wọn pé kí wọ́n ran àwọn lọ́wọ́. Owó ni wọ́n ń wá. Kìí ṣe pé kí wọ́n kọ ìwé tí kò ní í kú ni wọ́n fẹ́ ṣe. Kí wọ́n kọ ìwé tí yóò fún wọn owó ti wọn yóò fi jẹ àmàlà nìkan ló wà lọ́kàn wọn. Níbi tí ǹnkan ti lọ bó ṣe yẹ kó lọ, bí n bá dá ilé-ẹ̀kọ́ kan sílẹ̀ lórí bí a ṣ ń kọ̀wé lítíréṣọ̀ àtinúdá, ẹnìkankan ò níí wá síbẹ̀[rẹ́rìnín]. Wọn ò níí wá. Kí ni ìmóríyá fún wọn láti gbìyànjú kọ̀wé tí ó dára? Ṣé kí wọn kọ̀wé dáadáa kí wọ́n máa gba ẹgbẹ̀rún mẹ́ta lọ́dún

**Ṣoẹ̀tan:** Bí a bá tún fi ojú inú wòó, ó dàbí ẹni pé àwùjọ wa tún dákún ìṣòro tí ẹ mẹ́nubà yìí. Nítorí bí a bá wo àwọn orilẹ̀-èdè òke òkun gbogbo, àṣà kíkà piwé lítíréṣọ̀ gbilẹ̀ púpọ̀ ní àwọn ibi wọ̀nyìí. Ọpọ̀ ènìyàn tilẹ̀ ní àwọn òǹkọ̀wé tí wọ́n ń tẹ̀lé, yálà wọ́n jẹ́ ọmọ ilé-ẹ̀kọ́ ni o, tàbí wọ́n jẹ́ àgbàlagbà. Mo rò pé àwọn ènìyàn àtijọ́, ìyẹn ní àkókò tí irú yín wà lọ́dọ̀ọ́ kàwé ju àwọn ènìyàn òde-òní lọ ní ilẹ̀ wa

**Okediji:** Bẹ́ẹ̀ ni. Nítorí pé ìjọba ò tojúbọ̀ ìwé kíkọ. Kìí ṣe pé bí WAEC ò bá ti mú ìwé, ẹ ò rí owó kankan pa. Atótó Arére, ní ọ̀sẹ̀ tí ó kọká ni wọ́n fi sọ̀wédowó mi ránṣẹ́. Ó jẹ́ ẹgbẹ̀rún mẹ́ta Náírà àti ṣẹ́ńjì díẹ̀ fún odidi ọdún kan! Ní ọjọ́ kan, ní Birmingham, ní ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì, mo lọ kí òǹkọ̀wé kan, ìwé méjì

péré ló tíì kọ nígbà náà. Tí ó ba rí inú ibi tí ó ń gbé, ó fẹ́rẹ̀ tó gbogbo Mábalọ́jẹ́ yìí. Tí ó ní àwọn ààyè ìṣeré jànràn jànràn nínú ọgbà rẹ̀. Ó ní ìwé méjì péré lòún ṣì kọ, pé òun ń kọ ìkẹta lọ́wọ́. Báwo ló sì ti ṣẹlẹ̀? Tí ó bá ti kọ ìwé kan tán, tí ó gbé fún àwọn ilé-iṣẹ́ atẹ̀wétà. Bí wọ́n bá ti gbà láti tẹ̀ẹ́ jáde, àwọn ilé-ìtàwé, wọn ó ti baá sílẹ̀ lọ̀dọ́ òǹtẹ̀wé pé àwọn yóò fẹ́ tó bíi ẹgbẹ̀rún márùnún tàbí ẹgbẹ̀rún mẹ́fà ìwé ọhún. Ọjọ́ tí ìwé bá jáde gan-an ni wọn yóò ti tàá tán. Ilé-ìtàwé lẹ óò ti máa rí wọn. Ṣùgbọ́n níbí, ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́ báyìí ni pé èyí tí mo sọ pé ó kọ " ó ó ó " yẹn, bí ó bá ti kọ́ọ tán, kò ní fi ha ilé-iṣẹ́ atẹ̀wétà kankan kó yẹ̀ẹ́ wò. Fúnra rẹ̀ ló máa gbée fún àwọn atẹ̀wé aládàáni. Bí àwọn wọ̀ọ́yìí bá sì ti tẹ̀ẹ́ tán, ó wá ku bí òun yóò ṣe tàá. Tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ nígbà tí à ń lo ìlànà àwọn òyìnbó yẹn, tí o bá gbé ìwé rẹ ránṣẹ́ sí ilé -iṣẹ́ atẹ̀wétà bíi Longman, wọn á wá àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n onímọ̀ láti ka ìwé náà. Àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n yìí yóò wá sọ àkíyèsi àti èrò wọn lórí ìwé náà. Lẹ́yìn èyi, wọn yóò fi han òǹkọ̀wé láti ṣe àtúnsẹ. Bí òǹkọ̀wé bá faramọ́ èrò àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n náà, ó lè ṣe àtúnṣe sí ìwé rẹ̀. Bí kò bá sì faramọ́ àwọn èrò náà, kò ní ṣe àtúnṣe tí wọ́n sọ. Ó wá kù sí ọwọ́ ilé-iṣẹ́ atẹ̀wétà láti tẹ ìwé náà tàbí kí wọ́n má tẹ̀ẹ́. Ṣùgbọ́n lóde òni, òǹkọ́wé ti di atẹ̀wétà. Kò nìí fi han ẹnikẹ́ni tí yóò fi gbé e jáde. Bó bá sì ti fún àwọn àjọ tó ń mójútó ẹ̀kọ́ lówó, tí wọ́n ti yan ìwé e rẹ̀ fún ọdún méjì, tó bá ti tán, ìwé yẹn kú nìyẹn nítorí kò sí ẹlòmínìn tó wù.

**Ṣoẹtan:** Pẹ̀lú ipo yín àti ipa tí ẹ kó lórí lítíréṣọ̀ Yorùbá, o banilọ́kàn jẹ́ láti gbọ́ pé ẹgbẹ̀rún mẹta Nàíríà ní èrè tí wọ́n fún yín lọ̀dún kan fún \iṣẹ́ yín. Káni pé àwọn orílẹ̀-èdè bí i Gẹ̀ẹ́sì ni ẹ̀ ń gbé ni, ó dájú pé inú agbami owó ni ẹ òó wà báyìí. Ìbéèrè m i ni pe: ṣe àwọn ilé-iṣẹ́ atẹ̀wétà kìí tà ni, àbí kí ló dé tí wọ́n fi fún yin lẹ́gbẹ̀rún mẹ́ta lọ̀dún kan bí ẹ ti lókìkí tó?

**Okediji:** Àwọn ilé-iṣẹ́ atẹ̀wétà ò rí ọjà tà. Pàápàá jùlọ ìwé Yorùbá kìí tà. Nígbà tí mo fi wà ní Ifẹ̀, mo ní ilé-ìtàwé kan tó jẹ́ pé àwọn èèyàn máa ń ya wá láti ibi gbogbo lati wá ra ìwé ni. Ìdí ni pé mo máa ń ra àwọn ìwé tuntun sórí àtẹ. Iré ẹ̀ kò sí mọ́. Tí ẹ bá kó ìwé Yorùbá sí ibi kan, ta ló fẹ́ rà á? Nítorí náà, ilé-ìtàwé kan ò gbáralé à ń ta ìwé lítíréṣọ̀ Yorùbá. Kí ni àwùjọ wa náà ń ṣe? Wọ́n ní ebi ń pa mi, ọlọ́sẹ ń polówó. Ebi ń pa àwọn èèyàn, wọn ò ní owó tó ṣẹ́kù lápò láti fi ra ìwé. Ìkíní nìyẹn. Ìkejì, kò tilẹ̀ wá sí àwọn ìwé kan gidi mọ́ lọ́jà. Gbogbo ohun tó wà nísinsìnyí, ìjọba ti paákú. Ṣé èèyàn kan lè gba èrè ẹgbẹ̀rún mẹ́ta lọ̀dún kí ó wa sọ pé ìwé ló kù tí òun fẹ́ maa kọ? Ebi ló máa pákú, òun àti ẹbi ẹ̀! Ìwé kíkọ kò pé mọ́. Nígbà tí kò sì pé, àwùjọ ò tún wá lówó láti ràá. Ìwé tuntun ò jáde, àwọn tí wọ́n ò bá tún fẹ́ kàá kò lówó lọ́wọ́ láti ràá. A ò lè bá àwùjọ wí, wọn ò lówó lọ́wọ́. Kò tún pọn dandan láti ka ìwé Yorùbá ní ilé-ẹ̀kọ́ girama mọ́. Kìí ṣe òhun tí a lè gba ènìyàn nímọ̀ràn pé kí ó múra kí ó máa kọ̀wé. Ẹ fẹ́ fi ebi páa ni. Òǹkọ̀wé kan wà ní ìlú London, ó ní oṣù mẹ́ta péré lòun má fi ń

kọ̀wé lọ́dún kan.  Ó ní bí òun bá ti kọọ́ tán, tí òun gbée fún ilé-iṣẹ́ atẹ̀wétà, òun á wá rin ìrìnàjò yípo àgbáyé fún oṣù mẹ́sànán

**Ṣoẹtan:** Àwọn òǹkọ̀wé ilẹ̀ òkèrè máa ń gbowó lórí fíìmù àti àwọn ohun mìíran tí àwọn ilé-iṣẹ́ olókòwò bá gbé jáde láti inú iṣẹ́ wọn. Ìdí nìyí tí wọ́n máa fi ń ní owó púpọ̀ tí ó ń jẹ́ kí orí wọn yá sí ìwé kíkọ.

**Okediji:** Bẹ́ẹ̀ ni, gbogbo ẹ ló ń mú owó wá. Wale Adenuga bá mi ṣe *Rẹ́rẹ́ Rún* nígbà kan. Ó fún mi ni owó fún ẹ̀tọ́ òǹkòwé. Lọ́jọ́ òní báyìí, mo rò pé ilé-iṣẹ́ rédíò mẹ́fà ní ilẹ̀ Yorùbá  ló ń kàwé kan tàbí òmíràn bẹ́gẹ́ bí àyọkà àkàgbádùn tí wọ́n ò tilẹ̀ sọ fún mi rárá! Odidi Yunifásítì Ifẹ̀, ẹnikàn ní Èkó, Bọ̀dé Ọ̀sanyìn, ó túmọ̀ *Rẹ́rẹ́ Rún* sí èdè Gẹ̀ẹ́sì láìsọ fún mi. Àwọn ẹ̀ka-ẹ̀kọ́ tíátà ti Yunifasitì Ifẹ̀ wá ń ṣe eré náá káàkiri gbogbo ìlú Nàìjíríà. Mo wá sọ fún wọn pé wọn ò ṣée dáadáa. N ni wọ́n bá ni kì í ṣe ìwé mi ni àwọn ń ṣe , pé ìṣẹ́ Bọ̀dé Ọ̀sanyìn ni. Inú bi mi, mo bá gba ilé-ẹjọ́ lọ. Kóòtù sí dà mi láre, ìyẹn lẹ́yìn bí ọdún méjì. Èyí ṣẹlẹ̀ ní ọdú 1992. Ilé-ẹjọ́ wá ní ‘ki wọn fún mi ní ẹgbẹ̀rún lọ́nà ọgbọ́n Náírà. Ó jẹ́ owó ńlá nígbà náà. Ṣùgbọ́n ṣé tí àwọn ilé-iṣẹ́ rédíò wọ̀nyìí tí n kò mọ ibi tí wọ́n wà. Ju gbogbo ẹ̀ lọ, kò sí agbára mọ́ láti máa sáré kiri kóòtù báyìí

**Ṣoẹtan:** Mo rò pé ọ̀nà àbàyọ wà sí àwọn ìṣòro yìí. Àkọ́kọ́, mo rò pé a lè ta àwọn èèyàn jí sí mímọ àǹfàní tí ó wà nínú kíka àwọn lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ẹ̀ẹ̀kejì, ní èrò tèmi, mo rò pé a lè àwọn ìwé yìí sínú fọ́nrán ìgbohùn sílẹ̀ láti maa tà wọ́n fún àwọn òǹkàwé káàkiri  gbogbo àgbáyé. Ṣé ó ṣe e ṣe kí a rí ilé-iṣẹ́ kan tí ó lè gbé àwọn ìwé yìí jáde lọ́nàà yìí?

**Okediji:** Ẹnikan ti sọ ohun tí ó jọ bẹ́ẹ̀ fún mi rí, ṣùgbọ́n n kò mọ ìdí tí a kò fi tẹ̀síwájú  pẹ̀lu ètò náà. Àmọ́ ṣe kò ní dàbí Atótó Arére tí wọn ò tà yìí?

**Ṣoẹtan:** Ó tì! Ìlànà yìí yàtọ̀ gbáà. Ọ̀nà méjì ni ó lè pín sí. Ọ̀nà àkọ́kọ́ ni pé ó maa dàbí ẹni pé olorín fẹ́ gbé àwo orin jáde ni. Ọ̀nà kejì, bí a bá rí ọ̀jọ̀gbọ́n kan ní Yunifásitì tí ó lè ṣe agbátẹrù gbígbé àwọn àwo ìwé náà jádé yóò lè jẹ́ kí ó tùbọ̀ di ohun tí àwọn ènìyàn yóò máa rà kárí ayé.

**Okediji:** Ó dára bí a bá lè rí ìyẹn ṣe.

**Ṣoẹtan:** A óò gbìyànjú láti wá nǹkan ṣe. Lítíréṣọ̀ Yorùbá ò gbọdọ̀ parun!

**Okediji:** Bẹ́ẹ̀ ni, kò gbọdọ̀ parun. Ṣùgbọ́n a gbọ́dọ̀ gbárùkù

**Ṣoẹtan:** Ẹ ṣé sà. Ẹ kú òhùn láàtárọ̀. Àgbà yín á dalẹ́ o.

**Okediji:** Àmin! O ṣé púpọ̀.

- A kò mọ ọjọ́ pàtó tí wọ́n bí olóyè Ọládẹ̀jọ Òkédìjí. Ṣùgbọ́n wọ́n rò pé ní ọdún 1929 ni wọ́n bí wọn. Ìdí ni pé wọ́n ṣe ìsààmì onígbàgbọ́ ní ọdún 1930. Ọdún yẹn ló wà nínú ìwé ẹ̀rí ìtẹ̀bomi wọn. Wọ́n lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ láààrín ọdún 1935 sí ọdún 1943. Wọ́n sì di olùkọ́ nó ọdún 1944. Wọ́n lọ sí ilé ẹ̀kọ́ gíga Wesley College láti ọdún 1944 tításí di ọdún 1948. Wọ́n sì ṣiṣẹ́ olùkọ̀ọ́ ní ìpínlẹ̀ Ògùn, Ọ̀yọ́, Ẹkìtì, àti Èkó. Wọ́n fẹ́ ìyàwó ní ọdún 1953. Ní ọdún 1958 ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ní Ifẹ̀. Ibẹ̀ náà ni wọ́n sì wà títí di ọdún 1984 tí wọ́n fẹ̀yìntì. Wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí kọ ìwé Àjà Ló Lẹrù ní ìlú Àkúrẹ́ ní ọdún 1954, wọ́n sì gbée jáde ni ọdún 1969 pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n Adébóyè Babalọlá. Wọ́n ti fi ìgbà kan jẹ́ Káńsílọ̀ ní ìlù Ọ̀yọ́ rí.